An Phríomh-Oifig Staidrimh
Central Statistics Office

Yorùbá

# Ètò-Ìkànìyàn ni Ilẹ̀ Ireland

## Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́-Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin Ọdún 2011

Fọ̀ọ̀mù Ìtumọ̀-èdè

**Ètò-Ìkànìyàn 2011**
Èyí jẹ́ ìtumọ̀-èdè kan fún àwọn ìbéèrè inú Fọ̀ọ̀mù Ètò-Ìkànìyàn ti èdè Gẹ̀ẹ́sì. Jọ̀wọ̀ lo eyi gẹ́gẹ́ bí iranlọ̀wọ kan lati parí Fọ̀ọ̀mù Ètò-Ìkànìyàn rẹ. O gbọ́dọ̀ kọ àwọn idahun rẹ sórí ẹ̀yà Fọ̀ọ̀mù Ètò-Ìkànìyàn ti èdè Gẹ̀ẹ́sì tàbí ti Airiṣi sùgbọ́n o ní láti lo ìtumọ̀-èdè yìí gẹ́gẹ́ bí iranlọ̀wọ̀ kan ni.

**Nípa Ètò-Ìkànìyàn Náà**
Ètò-Ìkànìyàn ti ọdún 2011 náà yóò waye ni Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́-Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin ti a o si ka àwọn ènìyàn àti àwọn ìdílé gbogbo ti n bẹ ni orílẹ̀-èdè náà ni alẹ́-ọjọ́ náà. Eyi ni yóò jẹ́ ìkànìyàn kẹrinlelogun iru rẹ̀ láti ọdún 1841. Àwọn abajade ìkànìyàn yóò ṣafihan ipò ìbágbépọ̀ ati igbe-aye àwọn ènìyàn wa ni ẹkunrẹ́rẹ́, ti yóò si ran wa lọ́wọ́ lati ṣètò ọjọ́-iwaju.

**Ohun ti o ní Láti Ṣe**
Jọ̀wọ̀ pa fọ̀ọ̀mù yìí mọ́ si ibi ti ó pamọ́ daadaa, kí ó sìkọ ọ́ parí ni, alẹ́ Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́-Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin, ti i ṣe Alẹ́-ọjọ́ Ètò-Ìkànìyàn náà. O ní láti ka àwọn Àlàye Ìlanilọ́yẹ̀ ti n bẹ ni ojú-ewé ẹ̀yìn lati ran ọ lọ́wọ́ lati kọ fọ̀ọ̀mù náà parí. Ranti lati fọwọ́ sí ìbúra ti n bẹ ni ojú-ewé 23, kí ó sì gbaradì lati fi fọ̀ọ̀mù náà fún Olùkànìyàn rẹ.

**Ọ̀ranyàn ni Lábẹ́ Òfin Lati Kópa**
Èyí ni akiyesí lábẹ́ Abala 26 ti Òfin Àlàyé-Ìṣirò ti ọdún 1993. Ètò-Ìkànìyàn náà n waye lábẹ́ Òfin Àlàyé-Ìṣirò ti ọdún 1993 ati lábẹ́ Àṣẹ Àlàyé-Ìṣirò (Kíka Iye-ènìyàn) ti ọdún 2010. Lábẹ́ Abala 26 ati 27 ti Òfin Àlàyé-Ìṣirò ti ọdún 1993, òfin ṣe é ni ọ̀ranyàn fún ọ lati kọ fọ̀ọ̀mù náà parí, kí ó sì dá a padà**.** Ènìyàn yoowu ti ó ba kùnà tàbí kọ̀ lati pèsè àwọn àlàyé yìí tàbí tí ó mọ̀ọ̀mọ̀ fi àlàyé èké fún ni yóò sanwó ìtanràn ti ó le tó €25,000.

**A Fọwọ́sọ̀yà Ìboniláṣìríí**
Labẹ̀ òfin, Òfin Àlàyé-Ìṣirò ti ọdún1993 boni láṣìríí lorí ohukohun ti o kọ nipa ìkànìyàn rẹ. Ọ̀rọ̀ nipa àlàyé-ìṣirò nìkan ni Ọọ́fisi Ààrin-Gbùngbùn fún Àlàyé-Ìṣirò yóò lo àwọn àlàyé náà ti o pèsè fún. Ninú èyí ti agbejade àwọn àgbékalẹ̀ àlàyé-ìṣirò, àwọn ìjábọ̀ lórí àyẹ̀wò ati yíyan àwọn àpẹrẹ-ìṣẹ fún awọn ìwádìí wa kan.

**Olùkànìyàn Ètò-Ìkànìyàn rẹ**
Olùkànìyàn Ètò-Ìkànìyàn rẹ yóò ṣèrànwọ̀ fún ọ ti o ba ni awọn ìbéèrè nípa Ètò-Ìkànìyàn náà. Jọ̀wọ̀ fọwọ́sowọ́pọ̀ ni kíkun pẹ̀lú Olùkànìyàn rẹ lati rí i daju pe Ètò-Ìkànìyàn ti ọdún 2011 yọrí sí rere.

O ṣeun fún ìfọwọ́sowọ́pọ̀ rẹ



Gerard O'Hanlon
Olùdarí Gbogboogbò

**Tani Ó ní láti Parí Kíkọ Fọ̀ọ̀mù Ìkànìyàn Náà?**
Olórí-ìdílé tàbí ẹnikan àgbà kan nínú ìdílé náà ti n bẹ nílé ní alẹ́ Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́ Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin ní láti parí kíkọ fọ̀ọ̀mù náà. Fọ̀ọ̀mù Ìdílé kan n bẹ lọ́tọ̀ ti yóò jẹ́ kíkọ parí fún ìdílé kọ̀ọ̀kan.

Ìdílé kan ni:

- ènìyàn kan ti n dágbé, tàbí
- àpapọ̀ àwọn ènìyàn kan tí wọn bá ara wọn tan tàbí tí wọn kò bá ara wọn tan, tí wọn n jùmọ̀ gbe ni ojúlé kan náà pẹlu ipamọ ilé kan naa, eyi ti ó tumọ si pe, ó kere ju, wọn n jẹ oúnjẹ ẹ̀ẹkan papọ̀ lójúmọ́, ti wọn si n lo yàrà ìrẹjú tàbí yàrà ìgbàlejò kan papọ̀.

**Ṣe O Nilo Àwọn Afikun Fọ̀ọ̀mù Bi?**
Tí ó bá ju ìdílé kan lọ ti n gbe ni ojúlé yìí, béèrè lọ́wọ́ Olùkànìyàn rẹ fún Fọ̀ọ̀mù Ìdílé míràn.

Tí ẹ bá ju ènìyàn mẹfa lọ nínú ìdílé rẹ ni Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́-Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin, béèrè lọ́wọ́ Olùkànìyàn rẹ fún àfikún Fọ̀ọ̀mù Ẹlẹni-Kọ̀ọkan aláwọ̀-búlùù fún ènìyàn kọ̀ọ̀kan ti n bẹ pẹ̀lú yín.

**Bi O Ṣe le Kọ Fọ̀ọ̀mù Ìkànìyàn rẹ Parí**
1. Lo bírò Aláwọ̀-Dúdú tàbí Aláwọ̀-Búlùù.
2. Sàmì sí àwọn àpótí bí iru èyí
3. Tí o bá ṣe àṣìṣe kan, yanjú rẹ̀ báyìí ki o sì sàmì sí àpótí èyí tí ó yẹ.

Ní àwọn ibi tí ó yẹ kí o kọ àwọn ìdáhùn sí nínu, jọ̀wọ̀ lo ÀWỌN LẸ́TÀ ONÍPÒ-NLA, ki o sì fi àlàáfo sílẹ̀ sáàrin ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan. Tí ọ̀rọ̀ kan bá ju ààyè tí n bẹ lọ, tẹ̀síwájú sí ìlà tó kàn nìsàlẹ̀, fún àpẹrẹ:

| | | | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| H | O | T | E | L | | R | E | C | E |
| P | T | I | O | N | I | S | T | | |

**Jẹ́kí Fọ̀ọ̀mù rẹ Wà Nílẹ̀ fún Gbígbà á Padà**
Olùkànìyàn rẹ yóò padà wá laarin Ọjọ́-Ajé, Ọjọ́-Kọkanla Oṣù-Kẹrin sí Ọjọ́-Ajé, Ọjọ́ Kẹsan an Oṣù-Karun un lati gba fọ̀ọ̀mù rẹ tí o ti kọ parí lọ́wọ́ rẹ.

Tí fọ̀ọ̀mù rẹ bá si n bẹ lọ́wọ́ rẹ di Ọjọ́ Kẹsan an Oṣù-Karun un, jọ̀wọ̀ dá èyí tí o ti kọ parí padà si Ọọ́fisi Ààrin-Gbùngbùn Àlàyé-Ìṣirò, Àpótí Ifiweranṣẹ 2011, Freepost 4726, Swords, Co. Dublin.

**BẸ̀RẸ̀ NÍBÍ**

**H1 Irú ibùgbé wo ni ìdílé rẹ n gbé?**

*Sàmì sí ⊖ àpótí kan ṣoṣo.*

**Odindi ilé tàbí ilé-alábọ́dé kan, tó le jẹ:**

1 Abala-ilé
2 Ilé Kò-tó-odindi
3 Ilé-onífàrá-n-dà (tí ó ní ojúde)

**Ilé Fúláàtí tàbí ilé-alábọ́dé kan (pẹ̀lú dúpúlẹ́ẹ̀sì) tí ó jẹ́ aládàágbé:**

4 tí a kọ́ ní-pàto fun gbígbé ara-ẹni
5 tí ó jẹ́ ara ilé ti a yipada tàbí ibùgbé fún mímú owó wọle

**Ilé Oníbùsùn-kan:**

6 Ilé Oníbùsùn-kan (pẹ̀lú àwọn ohun-èlò ti a n pín lò f.a. ibi-ìgbọ̀nsẹ̀)

**Ibùgbé alágbèéká tàbí oní-fun-ìgbà-díẹ̀:**

7 ilé-bí-àpótí tàbí ibùgbé alágbèéká/fún-ìgbà-diẹ̀ míràn

**H2 Nigba wo ni a kọ́kọ́ kọ́ Ilé nàá?**

*Sàmì sí ⊖ ọdun ti a kọ́kọ́ kọ́ ilé nàá, kódà kó jẹ pe ile nàá ti paradà, di títúnkọ́ tàbí títúnṣe.*

1 Siwájú ọdún 1919
2 ìàárin ọdún 1919 – 1945
3 ìàárin ọdún 1946 – 1960
4 ìàárin ọdún 1961 – 1970
5 ìàárin ọdún 1971 – 1980
6 ìàárin ọdún 1981 – 1990
7 ìàárin ọdún 1991 – 2000
8 ìàárin ọdún 2001 – 2005
9 láti ọdún 2006 tàbí lẹ̀yìn rẹ̀

**H3 Ṣe ìdílé rẹ ni ó kọ́ ibùgbé rẹ tàbí ayálégbé ni yín?**

*Sàmì sí ⊖ àpótí kan ṣoṣo.*

1 Tiwa ti a yá owó kọ́ ni
2 Tiwa ni pátápátá
3 A n yá ilé gbé
4 A n yá ilé gbé ní ọ̀fẹ́

**Tí ẹ bá jẹ́ ayálégbé, tani onílé yin?**

1 Onílé aladáníi
2 Ìjọba Ìbílẹ̀
3 Ti ẹgbẹ́ Aláàánú/Alájẹ̀ṣẹ́kù kọ́lékọ́lé

**H4 Tí ẹ bá n yá ibùgbé yin gbé, èló ni ìdílé rẹ n san?**

Tẹ iye nàá nì ònkà-owó Euro wọlé sìbì.

€ □□□□□ • 0 0

*Sàmì sí ⊖ àpótí kan ṣoṣo.*

1 ní ọ̀sẹ̀-ọ̀sẹ̀
2 oṣooṣù
3 ọdọọdún

**H5 Awọn Yàrá Mélòó ni Ìdílé rẹ Nìkan n Lò?**

- *MÁṢE ka àwọn balùwẹ̀, ibi-ìgbọ̀nsẹ̀, àwọn ilé-ìdáná, àwọn yàrá-gbogbo-n̄-ṣe, àwọn yàrá àyẹ̀wò, àwọn ọ́ọ́fìsì, àwọn ìsọ̀, àwọn gbọ̀ngàn tàbí àwọn ibi-ìgbọ́kọ̀sí, tàbí àwọn yàrá tí wọn wà fún kíkó nnkan pamọ́ sí nìkan bí i àwọn kọ̀bọ́ọ̀dù.*
- *Ka gbogbo àwọn yàrá miran bí i àwọn ilé-ìdáná, àwọn yàrá-ìgbàlejò, àwọn yàrá-ìrẹjú, àwọn ilé-àfi-gíláàsì-kọ́ ti o le jokoo sí, àti àwọn yàrá-ìkàwé.*
- *Tí ẹ bá ti sọ àwọn yàrá meji di ọ̀kan, ẹ kà wọn gẹgẹ bí yàrá ọ̀kan ṣoṣo.*

Iye àwọn yàrá □□

**H6 Irú èlò-agbara wo ni ẹ maa n lò jù fún ẹ̀rọ dídá-ooru mú ibùgbé yin?**

*Sàmì sí ⊖ àpótí kan ṣoṣo.*

1 Ko si ẹ̀rọ dídá-ooru kankan
2 Epo
3 Atẹ́gùn àdáyebá
4 Iná-ijọba
5 Èédú
6 Eésan (pẹ̀lú koríko)
7 Atẹ́gùn-bí-Omi (LPG)
8 Igi (pẹ̀lú íṣẹ́pẹ́)
9 Àwọn míràn

**H7 Irú ìpèsè omi ẹ̀rọ wo ni n bẹ nínú ibùgbé rẹ?**

*Sàmì sí ⊖ àpótí kan ṣoṣo.*

1 A so mọ́ omi ẹ̀rọ láti orísun Gbogbogboò Nla kan
2 A so mọ́ Ètò Ìpèsè Omi Àpapọ̀ kan láti orísun ti Ìjọba Ìbílẹ̀ kan
3 A so mọ́ Ètò Ìpèsè Omi Àpapọ̀ kan láti orísun aladáníi kan (bí i kànga-dẹ̀rọ, adágún-omi, abbl.)
4 A so mọ́ orísun omi aladáníi míràn (bí i kànga, adágún-omi, àpọnmisí-nlá fun omi-ojò, abbl.)
5 Kò sí ìpèsè omi ẹ̀rọ kankan

**H8 Irú kòtò-ẹ̀gbin wo ni n bẹ ni ibùgbé rẹ?**

*Sàmì sí ⊖ àpótí kan ṣoṣo.*

1 Ètò kòtò-ẹ̀gbin ti gbogbogboò
2 Kòtò-ìgbọ̀nsẹ̀ ti olúkúlùkù
3 Ọ̀nà amojuto ẹ̀gbin miran yàtọ̀ si kòtò-ìgbọ̀nsẹ̀
4 Ìpèsè kòtò-ẹ̀gbin miran
5 Ko si ìpèsè kòtò-ẹ̀gbin

**H9 Àwọn ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ tàbí dánfó mélòó ni ẹnikan tàbí ju bẹẹ lọ nínú ìdílé rẹ ní tàbí tí wọ́n n lò?**

*Ka àwọn ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ tàbí dánfó ilé-iṣẹ́ tí n bẹ fún ìlò ara rẹ pẹlu mọ́ ọ.*

*Sàmì sí ⊖ àpótí kan ṣoṣo.*

1 Ọ̀kan
2 Méjì
3 Mẹ́ta
4 Mẹ́rin tàbí ju bẹẹ
5 Kòsí kankan

**H10 Ṣe ìdílé rẹ ní kọmputa ara-ẹni?**

1 Bẹ́ẹ̀ ni
2 Rárá

**H11 Ṣe ìdílé rẹ ní ààyè sí Intanẹ̀ẹti?**

*Sàmì 'Bẹ́ẹ̀ ni' sí ⊖ tí ẹ bá ní ààyè sí Intanẹ̀ẹti nínú ile rẹ.*

1 Bẹ́ẹ̀ ni, àsopọ̀mọ́ Burọọdubandi
2 Bẹ́ẹ̀ ni, àsopọ̀mọ́ míràn
3 Bẹ́ẹ̀ kọ́

**H12** ▶ **Lọ sí ojú-ewé tí ó kàn**

# GBOGBO ÀWỌN ÈNÌYÀN NI A GBỌ́DỌ̀ TI KÀ NÍBI TÍ WỌN WÀ NI ALẸ́ Ọ́JỌ́ ÈTÒ-ÌKÀNÌYÀN

**Àwọn àtòkọ méjì n bẹ̀ ní ìsàlẹ̀. Àtòkọ 1 wà fún àwọn ènìyàn tí ó wà nílé ní àdírẹ́sì yìí ní alẹ́ Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́-Kẹwàá, Ọsù-Kẹrin náà, ti i ṣe Alẹ́-ọjọ́ Ètò-Ìkànìyàn. Àtòkọ 2 sì wà fún àwọn ènìyàn tí n sáábà gbé ní àdírẹ́sì yìí sùgbọ́n tí wọn kò sí nibẹ ní alẹ́ Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́-Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin náà. Wo Àlàye Ìlanilọ́yẹ̀ nàá ti n so nipa Ìbéèrè 7 ni ojú-ewé ẹ̀yin fún ìtọ́nisọ́nà nipa itumọ ibugbé ìgbà-gbogbo ẹni.**

**ÀWỌN ÈNÌYÀN TÓ WÀ NÍLÉ**

**✓KỌ Ọ́ MỌ́ ARA Àtòkọ 1**

- Gbogbo àwọn ènìyàn ti n bẹ láàyè ní aago méjìlá òru Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́-Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin, tí wọn wà ní àdírẹ́sì yìí ní alẹ́ ọjọ́ náà.
- Àwọn ènìyàn tí wọn wà pẹlu ìdílé nàá fún ìgbà díẹ́ (èyí ni. awọn alejo).
- Àwọn ènìyàn tí wọn dé ní aarọ ọjọ́ keji sugbọn tí a kò tí ì kà níbòmíràn.

**✗MAṢE KỌ Ọ́ MỌ́ ARA Àtòkọ 1**

- Ènìyàn yoowu ti n gbé ni àdírẹ́sì yìí sùgbọ́n tí kò sí nílé fún ìgbà díẹ́ ni alẹ́ Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́-Kẹwàá náà, Oṣù-Kẹrin. Kọ àwọn ènìyàn yìí gẹ́gẹ́ bí ara àwọn tí kò sí nílé nínú Àtòkọ 2 ní ìsàlẹ̀.
- Àwọn àkẹ́kọ̀ọ́ tí kò sí nílé ní alẹ́ Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́-Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin náà. Kọ àwọn yìí gẹ́gẹ́ bí ara àwọn tí kò sí nílé nínú Àtòkọ 2 ní ìsàlẹ̀.
- Àwọn ọmọ-tuntun tí a bí lẹ̀yìn aago méjìlá òru Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́-Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin.

**ÀTÒKỌ 1 Àwọn ènìyàn TÍ Ó WÀ NÍLÉ nínú ìdílé nàá ni alẹ́ Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́-Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin**

| Nọ́mbà Ènìyàn | Orúkọ àkọ́kọ́ àti orúkọ-ìdílé |
|---|---|
| 1 | |
| 2 | |
| 3 | |
| 4 | |
| 5 | |
| 6 | |
| 7 | |
| 8 | |
| 9 | |
| 10 | |
| 11 | |
| 12 | |

Dáhùn àwọn ìbéèrè tí n sọ nípa ènìyàn kọ̀ọ̀kan tí ó wà nílé nínú ìdílé nàá ni Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́ Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin bẹ̀rẹ̀ lati Ojú-ewé 4 gẹ́gẹ́ bí a ṣe tò ó sílẹ̀ níbí.

Dáhùn àwọn ìbéèrè tí n sọ nípa àwọn ènìyàn ti n bẹ ni 7, 8, 9, abbl. sori àfikún Fọ́ọ̀mù Ẹlẹ́ni-Kọ̀ọ̀kan aláwọ̀-búlùù ti n bẹ lọ́dọ̀ Olùkànìyàn rẹ.

**ÀWỌN ÈNÌYÀN TÍ KÒ SÍ NÍLÉ**

**✓KỌ Ọ́ MỌ́ ARA Àtòkọ 2**

- Gbogbo àwọn ènìyàn tí n gbé ni àdírẹ́sì yìí ní gbogbo-gbà sùgbọ́n tí wọn kò sí nílé fún ìgbà díẹ́ ní Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́-Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin.
- Àwọn àkẹ́kọ̀ọ́ tí wọn wà ní ilé-ìwé tàbí ní kọ́lẹ́ẹ́jì.

**✗MAṢE KỌ Ọ́ MỌ́ ARA Àtòkọ 2**

- Ẹni yoowu ti o kọ mọ́ ara Àtòkọ 1.

**ÀTÒKỌ 2 Àwọn ènìyàn tí kò sí nílé, tí n gbé nínú ìdílé nàá nígbà-gbogbo**

| Nọ́mbà Ènìyàn | Orúkọ àkọ́kọ́ àti orúkọ-ìdílé |
|---|---|
| 1 | |
| 2 | |
| 3 | |
| 4 | |

Tí ó bá ju àwọn olùgbé ígbà-gbogbo mẹrin tí kò sí nílé ni alẹ́ Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́-Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin, jọ́wọ̀ béèrè lọ́wọ́ Olùkànìyàn rẹ fun ìtọ́nisọ́nà.

Dáhùn àwọn ìbéèrè, bẹ̀rẹ̀ ni Ojú-ewé 22 fún ọkọ̀ọ̀kan olùgbé ígbà-gbogbo tí a to orukọ wọn síbí gẹ́gẹ́ bí awọn tí kò sí nílé nínú ìdílé nàá ni alẹ Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́ Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin.nàá.

**1 Kín ni orúkọ rẹ? (Ènìyàn 1)**

*Orúkọ àkọ́kọ́ àti orúkọ-ìdílé.*

**2 Akọ-n-Bábo**

1 Akọ
2 Abo

**3 Kín ni ọjọ́ ìbí rẹ?**

Ọjọ́ Oṣù Ọdún

**Ìbéèrè yìí kò kan Ènìyàn 1 ninú ìdílé.**

**4 Kín ni ìbáṣepọ̀ rẹ pẹ̀lú Ènìyàn 1?**

| Ìbáṣepọ̀ ÈNÌYÀN 2 pẹ̀lú | Ènìyàn 1 |
|---|---|
| Ọkọ tàbí ìyàwó | 1 |
| Ẹnìkejì (ti ẹnìkejì sì le jẹ Akọ-n-Bábo kan naa) | 2 |
| Ọmọkùnrin tàbí ọmọbìnrin | 3 |
| Ọmọ-orogún | 4 |
| Arakúnrin tàbí arabìnrin | 5 |
| Ìyà tàbí bàbá | 6 |
| Òbí-àgbà | 7 |
| Ìyà/bàbá-keji | 8 |
| Àna-Ọmọkùnrin/Àna-ọmọbìnrin | 9 |
| Ọmọ-ọmọ | 10 |
| Ìbátan Míràn | 11 |
| Alábàágbépọ̀ (àti ọmọ àgbàtọ́ pẹ̀lú ) | 12 |

**5 Kín ni ipò lọ́kọ-laya rẹ ní lọ́wọ́lọ́wọ́ yìí?**

*Dáhùn tí ọjọ-ori bá tó ọdún 15 tàbí ju bẹẹ lọ.*
*Sàmì sí àpótí kan ṣoṣo.*

1 Àpọ́n (kò ṣe ìgbéyàwó rí)
2 Ti ṣe ìgbéyàwó (ìgbéyàwó àkọ́kọ́)
3 Ti tun ìgbéyàwó ṣe (lẹ́yìn opó)
4 Ti tun ìgbéyàwó ṣe (lẹ́yìn ìkọrasílẹ̀/ títu- ìgbéyàwó-ká)
5 TiPínyà (jíjára-ẹni-jù-sílẹ̀ wà lara wọn)
6 Ìkọrasílẹ̀
7 Ti di Opó

**6 Ilu wo ni wọn bí ọ sí?**

*Darukọ ibi ti ìyà rẹ n gbe nigba ti wọn bí ọ.*
Tí ó bá jẹ́ IRELAND ni (Àríwá Ireland wà lara wọn)
kọ AGBÈGBÈ nàá síbí

Tí ó bá jẹ́ níbòmíràn NÍ ILẸ̀ ÒKÈÈRÈ, kọ ORÍLẸ̀-ÈDÈ nàá síbí.

**7 Níbo ni o n fi ígbà-gbogbo gbé?**

1 Ni àdírẹ́sì yìí NÍBÍ
2 Níbòmíràn ní IRELAND (Àríwá Ireland wà lara wọn) kọ ÀDÍRẸ́SÌ NÍ KÍKÚN rẹ síbí
3 Níbòmíràn NÍ ILẸ̀ ÒKÈÈRÈ, kọ ORÍLẸ̀-ÈDÈ nàá síbí

**8 Níbo ni o n fi gbogbo-ìgbà gbé lati bi ọdún kan sẹ́yìn?**

*Dáhùn tí ọjọ-ori bá tó ọdún 1 tàbí ju bẹẹ lọ*

1 IBI kan nàá di ìsinyìí
2 Níbòmíràn ní IRELAND (àti Àríwá Ireland pẹ̀lú) kọ AGBÈGBÈ nàá síbí
3 Níbòmíràn NÍ ILẸ̀ ÒKÈÈRÈ, kọ ORÍLẸ̀-ÈDÈ nàá síbí

**9 N jẹ̀ o ti gbé ẹ̀yìn-odi Ilẹ̀ Ireland nìkan fún odindi ọdún kan tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ?**

*Dáhùn tí ọjọ-ori bá tó ọdún 1 tàbí ju bẹẹ lọ, ti o si n gbe ni Ireland.*

1 Bẹ́ẹ̀ ni
2 Bẹ́ẹ̀ kọ́

Tó bá jẹ́ **'Bẹ́ẹ̀ ni'**, kọ ỌDÚN nàá ti o gba ilé gbẹ̀yìn ní Ilẹ̀ Ireland síbí

ÀTI

ORÍLẸ̀-ÈDÈ nàá ti o gba ilé sí gbẹ̀yìn.

**10 Níbo ni orilẹ̀-èdè-abínibí rẹ?**

*Tí o bá ni ju orilẹ̀-èdè-abínibí kan lọ, jọ́wọ̀ jẹ ki a mọ gbogbo wọn.*

1 Ọmọ-Ilẹ̀ Ireland
2 ORILẸ̀-ÈDÈ ABÍNIBÍ Míràn, kọ ọ́ sí ibí
3 Kòsí orilẹ̀-èdè-abínibí kankan

**11 Kín ni ẹ̀yà-èdè tàbí àṣà àtilẹ̀wá rẹ?**

*Yan ỌKAN láti isọri A sí D, lẹyin náà, sàmì sí àpótí náà tó yẹ.*

**A Aláwọ̀-Funfun**

1 Ọmọ-Ilẹ̀ Ireland
2 Arìnrìn-àjò Ọmọ-Ilẹ̀ Ireland
3 Èyíkèyí Aláwọ̀-Funfun míràn

**B Aláwọ̀-Dúdú tàbí Aláwọ̀-Dúdú Ọmọ-Ilẹ̀ Ireland**

4 Ọmọ-Ilẹ̀ Afirika
5 Èyíkèyí Aláwọ̀-Dúdú míràn

**C Ọmọ-Ilẹ̀ Ésíà tàbí Ọmọ-Ilẹ̀ Ésíà ti Ilẹ̀ Ireland**

6 Ọmọ-Ilẹ̀ Ṣáínà
7 Èyíkèyí Ọmọ-Ilẹ̀ Ésíà míràn

**D Awọn Míràn, tí Oníruurú Orílẹ̀-èdè ayé wà lara wọn**

8 Awọn míràn, kọ àpéjúwe rẹ̀ sí ibí

**12 Ẹ̀sìn wo ni tìrẹ?**

*Sàmì sí àpótí kan ṣoṣo.*

1 Katoliki
2 Ṣọ́ọ̀ṣì ti Ilẹ̀ Ireland
3 Ìsìláàmù
4 Ìjọ Purẹsibiteriani
5 Ẹ́lẹsìn Kiristiẹni-Àtijọ́
6 Òmíràn, kọ ẸSÌN rẹ sí ibí
7 N kò ní Ẹ̀sìn

**13 Mélòó ní àwọn ọmọ tí o ti bí?**

*Ìbéèrè yìí wà fún àwọn obìrin nìkan.*
Kọ iye àwọn ọmọ tí o bí láàyè.

1 N Kò bí kankan

**14 N jẹ̀ o le sọ Èdè Áírí̀ṣì?**

*Dáhùn tí o bá jẹ ọmọ ọdún 3 tàbí sókè.*

1 Bẹ́ẹ̀ ni
2 Bẹ́ẹ̀ kọ́

**Tó bá jẹ́ 'Bẹ́ẹ̀ ni', ṣe o n sọ Èdè Áírí̀ṣì?**

*Sàmì sí àwọn àpótí náà ti o yẹ.*

1 Lójúmọ, láàrin ètò ẹ̀kọ́ náà
2 Lójúmọ, láìjẹ mọ́ ti ètò ẹ̀kọ́
3 Ni ọ̀ṣọ̀ọ̀ṣẹ̀
4 Tí kì í ṣe gbogbo ígbà
5 Laelae

**15 Ṣe o n sọ èdè míràn yàtọ̀ sí Èdè Gẹ̀ẹ́sì tàbí Èdè Áírísì nínú ilé?**

1 Bẹ́ẹ̀ ni

2 Bẹ́ẹ̀ kọ́ ► Lọ sí ÌBRÈ 16

**Èdè wo ni èdè náà?**

(f.a. ÈDÈ POLANDI, ÈDÈ JAMANI, ÈDÈ ÁÍRÍṢÌ, ÈDÈ ÀWỌN ODI)

**Báwo ni o ṣe gbọ́ Èdè Gẹ̀ẹ́sì tó?**

*Sàmì sí àpótí kan ṣoṣo.*

1 Dáradára gan an

2 Dáradára

3 Kò dára tó

4 Kò dára rárá

**16 N jẹ́ o ni ọ̀kan nínú awọn ipò àìlera tàbí awọn ìṣoro ọlọ́jọ́-pípẹ́ náà ti a kà si isalẹ yìí?**

| | Bẹ́ẹ̀ ni | Bẹ́ẹ̀ kọ́ |
|---|---|---|
| (a) Ìfọ́jú tàbí àìríran dáadáa | | |
| (b) Yìya-odi tàbí àìgbọ́ràn dáadáa | | |
| (c) Irufẹ ìṣoro kan pẹ̀lú àwọn nnkan pẹ́pẹ̀ẹ̀pẹ́ ti a n fi ara ṣe, bí i ìrìn, gígun pẹ̀tẹ́ẹ̀sì, nínàgà, gbígbé nnkan soke tàbí gbígbé ẹrù, | | |
| (d) Àìlèlo- ọpọlọ dáadáa | | |
| (e) Ìṣoro kan pẹ̀lú kíkọ́-ẹ̀kọ́, ṣíṣe ìrántí tàbí àfọ́kànsí | | |
| (f) Ipò ti n ṣe àkóbá fun lílo ọgbọ́n-inú tàbí fun ìmọ̀lára | | |
| (g) Ìṣoro kan pẹ̀lú ìrora, mímí èémí, tàbí èyíkèyí àìsàn-líle tàbí ipò míràn | | |

**17 Tí ó bá jẹ́ 'Bẹ́ẹ̀ ni' fun èyíkèyí àwọn isọri náà ti a sọ ni-pato ní Ìbéèrè 16, n jẹ́ o ní ìṣoro nípa ṣíṣe èyíkèyí nínú àwọn nnkan náà bí?**

| | Bẹ́ẹ̀ ni | Bẹ́ẹ̀ kọ́ |
|---|---|---|
| (a) Wíwọ aṣọ, wíwẹ̀ tàbí lílọ-bíbọ̀ nínú ilé náà | | |
| (b) Didá jáde lọ kúrò nínú ilé náà lati lọ ra nnkan tàbí lati ṣàbẹ̀wò si ilé-iṣẹ́ abẹ dokita | | |
| (c) N ṣiṣẹ́ níbi iṣẹ́ kan tàbí n ṣòwò tàbí n lọ sí ilé-ìwé tàbí kọ́lẹ́ẹ̀jì | | |
| (d) N kópa nínú awọn akitiyan míràn, fún àpẹrẹ fàájì tàbí lílò ìgbòkègbodò-ọkọ̀ | | |

**18 Báwo ni alaafia rẹ lákòótán?**

*Sàmì sí àpótí kan ṣoṣo.*

1 Ó ṣe dééédéé gan an

2 Ó ṣe dééédéé

3 Ó ṣe díẹ̀

4 Kò ṣe dééédé

5 Kò ṣe dééédéé rárà

**19 Báwo ni o ṣe maa n dé ibi iṣẹ́, ilé-ìwé tàbí kọ́lẹ́ẹ̀jì nígbà-gbogbo?**

*Sàmì sí àpótí kan ṣoṣo, fún èyí ti ó gun julọ, nínú ìrìn-àjò rẹ lọ sí ibi iṣẹ́ , ilé-ìwé tàbí kọ́lẹ́ẹ̀jì .*

1 N kò sí ni ibi iṣẹ́, ilé-ìwé tàbí kọ́lẹ́ẹ̀jì

2 ìrìn ẹsẹ̀

3 Kẹ̀kẹ́

4 Moluẹ, dánfó tàbí ọkọ̀-ẹlẹ́sin

5 ọkọ̀-ojuúrin, DART tàbí LUAS

6 Alùpùpù tàbí ẹlẹ́sẹ̀-mẹta

7 Wíwa ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ kan

8 Èrò inú ọkọ̀-ayọ́kẹ́lẹ́ kan

9 Dánfó

10 Omíràn, ọkọ̀-akẹ́rù wà lara wọn

11 N ṣiṣẹ́ ní ilé tàbí láti ilé nikan

**20 Bí àsìkò wo ni o ma n sáábà kúrò ni ilé láti lọ sí ibi iṣẹ́, ilé-ìwé tàbí kọ́lẹ́ẹ̀jì?**

1 N kò sí ni ibi iṣẹ́, ilé-ìwé tàbí ní kọ́lẹ́ẹ̀jì

2 Siwájú 06:30

3 06:30–07:00

4 07:01–07:30

5 07:31–08:00

6 08:01–08:30

7 08:31–09:00

8 09:01–09:30

9 Lẹ́yìn 09:30

**21 Báwo ni ìrìn-àjò rẹ lọ́ si ibi iṣẹ́, ilé-ìwé tàbí kọ́lẹ́ẹ̀jì ṣe maa n sáábà gùn tó?**

Kọ ọ́ ni ìṣẹ́jú.

**22 Ṣe o maa n pèsè ìrànwọ̀ gbogbo-ìgbà fún ọrẹ́ tàbí ara inú ẹbí kan tí ó ní àìsàn, ìṣoro ìlera tàbí àìpé-ara ọlọ́jọ́-pípẹ́ kan láìgba owó?**

*Kọ awọ́n ìṣoro ti o ní í ṣe pẹ̀lú jíjẹ́ arugbó mọ́ ọ. Ríran ni lọ́wọ̀ nínú awọ́n iṣẹ́ pẹ́pẹ̀ẹ̀pẹ́ bí gbígbé ounjẹ̀ sí ènìyàn lẹ́nu tàbí wíwọ aṣọ fún ènìyàn wà lara awọ́n ṣiṣèrànwọ̀ náà.*

1 Bẹ́ẹ̀ ni

2 Bẹ́ẹ̀ kọ́

**Tó bá jẹ́ 'Bẹ́ẹ̀ ni', ó tó wákàtí mélòó ni nínú ọ̀ṣẹ̀ ?**

Kọ ọ́ ní wákàtí.

**23 Tí ọjọ́-orí rẹ kò bá tó ọdun 15**

► **Lọ sí ÌBRÈ34**

**24 N jẹ́ ìgbà kan n bẹ ti o dáwọ́ ẹ̀kọ́ alàsìkò-kíkún rẹ dúró bí?**

1 Bẹ́ẹ̀ ni

2 Bẹ́ẹ̀ kọ́

**Tó bá jẹ́ 'Bẹ́ẹ̀ ni', kọ iye ọjọ́-orí rẹ ní ìgbà náà ti o dáwọ́ rẹ̀ dúró.**

**25 Kín ni ìpele ẹ̀kọ́/ẹ̀kọ́-ṣẹ́ náà (ní-kíkún-àsìkò tàbí abala-àsìkò) tó ga júlọ tí o ti parí di ìsìnyí?**

*Sàmì sí àpótí kan ṣoṣo.*

1 Emi kò ni ẹ̀kọ́/ẹ̀kọ́-ṣẹ́ eléto kankan

2 Ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀
Àwọn ìpele 1 tàbí 2 ti NFÌBRÈ
*Ìwé-ẹ̀rí Ìpele 1 tàbí 2 ti FETAC tàbí ọ̀kan náà bí i rẹ̀*

3 Ẹ̀kọ́ Sẹ́kọ́ndírì Kekere
Ìpele 3 ti NFÌBRÈ
*Ìwé-ẹ̀rí Kekere/Agbede-meji/Àlápapọ̀, ti Ìpele 3 ti FETAC*
*Ìwé-ẹ̀rí, Àwọn Ọgbọ́n-orí Akọ́kọ̀mọ̀ TI FÁS,*
*Ìwé-ẹ̀rí Ìpìlẹ̀ ti NCVA tàbí ọ̀kan náà bí i rẹ̀*

4 Ẹ̀kọ́ Sẹ́kọ́ndírì Àgbà
Àwọn ìpele 4 tàbí 5 ti NFÌBRÈ
*Ìwé-ẹ̀rí Ìkẹ́kọ̀ọ́jáde (tí Ètò-Ẹ̀kọ́ Ijinlẹ̀ àti Ẹ̀kọ́-ṣẹ́ ọwọ́ wà lara wọn) tàbí ọ̀kan náà bí i rẹ̀*

5 Ẹ̀kọ́ iṣẹ́-ẹ̀rọ tàbí Ẹ̀kọ́-ṣẹ́ ọwọ́
Àwọn ìpele 4 tàbí 5 ti NFÌBRÈ
*Ìwé-ẹ̀rí Ìpele 4/5 FETAC, Ìpele 1/2 ti NCVA, Ọgbọ́n-orí Àkànṣe ti FÁS, Ìwé-ẹ̀rí Teagasc nínú Ẹ̀kọ́ Iṣẹ́-agbẹ̀, Ìwé-ẹ̀rí Ẹ̀kọ́ Iṣẹ́-ọnà ti CERT tàbí ọ̀kan náà bí i rẹ̀*

6 Ìwé-ẹ̀rí Tó-jinlẹ̀-jùlọ/Ìparí Ìkọ́ṣẹ́
Ìpele 6 ti NFÌBRÈ
*Ìwé-ẹ̀rí Tó-jinlẹ̀-jùlọ ti FETAC, Ìpele 3 ti NCVA Ìwé-ẹ̀rí Iṣẹ́-ọnà ti Orílẹ̀-èdè ti FÁS, Ìwé-ẹ̀rí Teagasc nínú Ẹ̀kọ́ Iṣẹ́-ọgbìn, Ìwé-ẹ̀rí CERT ti Ẹ̀kọ́ Akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ Alásè tàbí ọ̀kan náà bí i rẹ̀*

7 Ìwé-ẹ̀rí Tó-ga-jùlọ
Ìpele 6 ti NFÌBRÈ
*Ìwé-ẹ̀rí NCEA/HETAC ti Orílẹ̀-èdè tàbí ọ̀kan náà bí i rẹ̀*

8 Ìkẹ́kọ̀ọ́gboyè Báṣẹ́lọ̀ Lásán tàbí Dipuloma Ti Orílẹ̀-èdè
Ìpele 7 ti NFÌBRÈ

9 Ìwé-ẹ̀rí Ìdánilọ́la Ìkẹ́kọ̀ọ́gboyè Báṣẹ́lọ̀/ Ìwé-ẹ̀rí Akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ tàbí méjééjì
Ìpele 8 ti NFÌBRÈ

10 Dipuloma Yunifasiti tàbí Ìkẹ́kọ̀ọ́gboyè
Ìpele 9 ti NFÌBRÈ
Dipuloma Yunifasiti, Ìkẹ́kọ̀ọ́gboyè Masitasi tàbí ọ̀kan náà bí i rẹ̀

11 Ìkẹ́kọ̀ọ́gboyè-Ọ̀mọ̀wé (Ph.D) tàbí
Ìpele 10 ti NFÌBRÈ

**26 Ẹ̀ka ìmọ̀ ẹ́kọ́ tó ga jùlọ wo gan an gan an ni o ti parí ìkẹ́kọ̀ọ̀gboyè tìtí di ìsìnyí?**

*Láì ka ìkẹ́kọ̀ọ̀jáde Ilé-ẹ̀kọ́ Sẹ́kọ́ndírì mọ́ ọ.*

Kọ ẹ̀ka ìmọ̀ ẹ́kọ́ náà

(f.a. Ẹ̀KỌ́ ÌṢIRÒ-OWÓ, Ẹ̀KỌ́ ẸWÀ ATI OGE ṢÍṢE, Ẹ̀KỌ́ ÌṢẸ́-ỌGBÌN, Ẹ̀KỌ́ ÌṢẸ́-ẸRỌ-OMI)

**27 Báwo ni o ṣe le ṣàpéjúwe ipò náà gan an ti o wà lọ́wọ́lọ́wọ́ yìí?**

*Sàmì sí àpótí kan ṣoṣo.*

1 N ṣiṣẹ́ fún owó tàbí fún èrè

2 N wa iṣẹ́ àkọ́kọ́ tó le mú owó wọle deedee

3 Àìníṣẹ́-lọ́wọ́

4 Akẹ́kọ̀ọ̀ tàbí ọmọ ile-iwe

5 N mojuto ìdílé/ẹbí

6 Ti fẹ̀yìntì lẹ́nu iṣẹ́

7 Kò le ṣiṣẹ́ nitori àìsàn kò-gbóògùn tàbí jíjẹ́ aláàbọ̀-ara

8 Òmíràn, kọ ọ́ sí ibí

**28 Tí o bá n ṣiṣẹ́ ,**

**àìníṣẹ́-lọ́wọ́ tàbí ti fẹ̀yìntì** ▶ **Lọ sí ÌBRÈ 29**

**Tí o bá jẹ́ akẹ́kọ̀ọ̀ kan** ▶ **Lọ sí ÌBRÈ 34**

**Bi bẹ̀ẹ̀ kọ** ▶ **Lọ sí ÌBRÈ 35**

**29 Ṣe o n (ti) ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí abáni-ṣiṣẹ́ kan tàbí o (ti) jẹ oníṣẹ́-ara-ẹni nínu kókó iṣẹ́ rẹ?**

Kókó iṣẹ́ rẹ ni iṣẹ́ náà tí o ti maa n lo wákàtí tí o gùn julọ.

*Sàmì sí àpótí kan ṣoṣo.*

1 Abáni-ṣiṣẹ́

2 Oníṣẹ́-ara-ẹni, pẹlu awọn abáni-ṣiṣẹ́ tó n sanwó fun

3 Oníṣẹ́-ara-ẹni, láìní awọn abáni-ṣiṣẹ́ ti n sanwó fun

4 N ṣiṣẹ́ lati ṣèrànwọ̀ fun ìbátan kan (láì gba owó ojúmọ́ tàbí owó oṣù)

**30 Kín ni ojúṣe ní bi iṣẹ́ rẹ náà?**

*Ní gbogbo ọna ṣàpéjúwe ojúṣe náà ní-kíkún, kí ó sìsọ ipo-iṣẹ́ náà ní-pàtó.*

| Lo awọn ọ̀rọ̀ bí i | MAṢE lo ọ̀rọ̀ gbogboogbò bí i |
|---|---|
| ALÁMÒJÚTÓ Ọ́JÀ TÍTÀ | ALÁMÒJÚTÓ |
| OLÙKỌ́ ILÉ- Ẹ̀KỌ́ SẸ́KỌ́NDÍRÌ | OLÙKỌ́ |
| ONÍṢẸ́-ẸRỌ́ INÁ | ONÍṢẸ́-ẸRỌ́ |

*Oṣiṣẹ́ ijọba àti abáni-ṣiṣẹ́ ijọba ibilẹ ní láti sọ ipo wọn ní-pàtó f.a. AKỌWE AGBA. Ki awọn Gardaí tàbí Ẹ̀ṣọ́-Ológun náà ní láti sọ pàtó ipo wọn. Awọn Olùkọ́ náà ní láti sọ ẹ̀ka ìkọ́nilẹ́kọ̀ọ́ wọn f.a. OLÙKỌ́ ALÁKỌ̀Ọ̀BẸ̀RẸ̀. Awọn alufaa àti oníṣẹ́ ẹ̀sìn pẹlu ní láti ṣàpéjúwe ní-kíkún e.g. ALUFAA-BINRIN, OLUTỌJU-ALAISAN GBOGBO-N-ṢE.*

Kọ OJÚṢE rẹ gan an gan an sí ibí

**Tí o bá jẹ́ agbẹ**, kọ TITOBI OKO ti o n dá náà ní Hẹkita

Titobi ní Hẹkita

**31**

**Tí o bá ti fẹ̀yìntì** ▶ **Lọ sí ÌBRÈ 35**

**32 Kín ni irú-iṣẹ́ ti agbaniṣíṣẹ́ rẹ gbekalẹ níbi tí o ti n ṣiṣẹ́ bayii (tẹ̀lẹ́)?**

*Tí ó bá jẹ oníṣẹ́-ara-ẹni ní ọ bayii (tẹ̀lẹ́) dáhùn ní ilana pẹlu bí irú-iṣẹ́ rẹ ti rí.*

*Ṣàpéjúwe irú ọjà tàbí íṣẹ́ náà ti agbaniṣíṣẹ́ rẹ n gbe ṣe*

Fún àpẹrẹ, ṢÍṢE AWỌN KỌMPUTA, TITUN AYỌ́KẸ́LẸ́ ṢE, Ẹ̀KỌ́ SẸ́KỌ́NDÍRÌ, TITA OUNJẸ LOJÚ-PÁÁLÍ, ILE-IṢẸ́ APOÒGÙN, AGBAṢẸ́ṢE KÓLẸ̀-KÓ-DỌ̀TÍ, ÈLÒ-IṢẸ́ KỌMPUTA, IDAGBASOKE, ÀTI ATILẸYIN.

**33**

**Tí o bá jẹ́ Alàìníṣẹ́-lọ́wọ́** ▶ **Lọ sí ÌBRÈ 35**

**34 Kín ni náà ORÚKỌ àti ÀDÍRẸ́SÌ ibi iṣẹ́, ilé-ìwé tàbí kọ́lẹ́ẹ́jì rẹ NÍ-KÍKÚN?**

**Orúkọ Ní-Kíkún**

**Àdírẹ́sì**

1 N ṣiṣẹ́ ninu ilé tàbí láti ilé 2 Kò ni ibi iṣẹ́ kan pàtó

**35 Dáhùn àwọn ìbéèrè fún Ènìyàn 2 bẹ̀rẹ̀ lati ojú-ewé náà tó kàn.**

**Tó bá jẹ́ ẹnikan ṣoṣo ní ó wà nílé ninu ìdílé náà ni alẹ́ Ọjọ́-Kẹwàá Oṣù-Kẹrin** ▶ **Lọ sí ojú-ewé 22**

# Àlàye Ìlanilọ́yẹ̀

**Dáhùn àwọn ìbéèrè A1 sí A8 fún gbogbo ará-inú ìdílé tí n gbé àdírẹ́sì yìí ní ígbà-gbogbo sùgbọ́n tí KÒ SÍ nílé ní alẹ́ of Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́-Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin náà. Fi gbogbo àwọn akẹ́kọ̀ọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀, ilé-ẹ̀kọ́ Sẹ́kọ́ndírì àti àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ìpele kẹta ti wọn n gbé jinna si ilé ni àsìkò sáà tí wọn KÒ SÍ nílé ní àdírẹ́sì yìí ní alẹ́ Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́-Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin náà.**

**Ènìyàn Tí kò sí nílé**

**A1 Kín ni orúkọ ènìyàn yìí?**
*Orúkọ àkọ́kọ́ àti orúkọ-ìdílé.*

**A2 Akọ-n-Bábo**

1 Akọ 2 Abo

**A3 Kín ni ọjọ́ ìbí ènìyàn yìí?**

Ọjọ́ Oṣù Ọdún

**A4 Kín ni náà ìbáṣepọ̀ ènìyàn yìí pẹ̀lú Ènìyàn 1 ní ojú-ewé 4?**
*Sàmì sí ⊖ àpótí kan ṣoṣo.*

1 Ọkọ tàbí ìyàwó
2 Ẹnìkejì (ti ẹnìkejì sì le jẹ Akọ-n-Bábo kan náà)
3 Ọmọkùnrin tàbí ọmọbìnrin
11 Ìbátan míràn, kọ ÌBÁṢEPỌ̀ sí ibí
12 Alábàágbépọ̀ (àti ọmọ àgbàtọ́ pẹ̀lú)

**A5 Kín ni ipò lọ́kọ-láya ènìyàn yìí ní lọ́wọ́lọ́wọ́ yìí?**
*Dáhùn tí ọjọ-ori bá tó ọdún 15 tàbí ju bẹẹ lọ..*
*Sàmì sí ⊖ àpótí kan ṣoṣo.*

1 Àpọ́n ( kò ṣe ìgbéyàwó rí)
2 Ti ṣe ìgbéyàwó (tí-tún ìgbéyàwó ṣe wà lara wọn)
5 Ti Pínyà (jíjára-ẹni-jù-sílẹ̀ wà lara wọn)
6 Ìkọrasílẹ̀
7 Ti di Opó

**A6 Ó tó igba wo lapapọ́ ti ènìyàn yìí kuro nile?**

1 Ó din ni oṣù 12
2 Oṣù 12 tàbí ju bẹẹ lọ

**A7 Ǹ jẹ́ ènìyàn yìí wà ní Ilẹ̀ Ireland ní Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́-Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin?**

1 Bẹ́ẹ̀ ni
2 Bẹ́ẹ̀ kọ́

**A8 Ǹ jẹ́ ènìyàn yìí wà nílé-ìwé tàbí kọlẹ́ẹ̀jì kan bí i akẹ́kọ̀ọ́ bí?**

1 Bẹ́ẹ̀ ni
2 Bẹ́ẹ̀ kọ́

**Ìbúra fún ènìyàn náà ti o wà ni ipo lati kọ náà fọ́ọ̀mù parí.**

**Siwájú kí o tó fọwọ́ sí i ìbúra náà, jọ́wọ̀ yẹ ẹ wo:**

- Pe o pari àwọn ìbéèrè náà nípa ibùgbé rẹ ni Ojú-ewé 2.
- Pe ní Àtòkọ 1 ní Ojú-ewé 3, o ti dáhùn fún gbogbo àwọn ènìyàn (ati àwọn alejo pẹlu) tí wọn sùn ní àdírẹ́sì yìí ní alẹ Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́ Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin náà.
- Pe o ti dáhùn gbogbo àwọn ìbéèrè ti o ní lati dáhùn fún ọ̀kọ̀ọ̀kan ènìyàn náà tí wọn sùn ní àdírẹ́sì yìí ní alẹ Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́ Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin náà ní ìdílé náà (àwọn Ojú-ewé 4 sí 21).
- Pe ní Àtòkọ 2 loju Ojú-ewé 3, o ti dáhùn fún gbogbo àwọn ènìyàn tí n gbé àdírẹ́sì yìí ní ígbà-gbogbo sùgbọ́n tí wọn kò sí nílé fún ìgbà díẹ́ ní Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́ Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin.
- Pe o ti dáhùn gbogbo àwọn ìbéèrè ni àwọn Ojú-ewé 22 sí 23 fún gbogbo àwọn ará-inu ìdílé tí kò sí nílé fún ìgbà díẹ́ ni alẹ Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́ Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin náà.
- Pe kò sí ènìyàn kan tí a ká ni ẹ̀ẹ̀mejì lori fọ́ọ̀mù náà.

Mo bura pe fọ́ọ̀mù yìí tọ̀nà, ó sì péye, pẹlu ìmọ̀ àti igbagbọ mi.

Ìfọwọ́sí

**Bayii, o ti pari fọ́ọ̀mù Ìkànìyàn náà.**
**O ṣeun fún ìfọwọ́sowọ́pọ̀ rẹ.**

**Tí ó bá ju àwọn ènìyàn 4 tí kò sí nílé fún ìgbà díẹ́ láti náà ìdílé ni alẹ of Ọjọ́-Àìkù, Ọjọ́ Kẹwàá, Oṣù-Kẹrin náà, jọ́wọ̀ lọ́wọ́ bèèrè Olùkànìyàn rẹ fún ìtọ́nisọ́nà.**

# Àlàye Ìlanilọ́yẹ̀

**Ìbéèrè H3 – Ṣe ti ìdílé rẹ ni ibùgbé rẹ tàbí ẹ n yálé gbé?**
Tí ẹ bá n yálé ibùgbé rẹ gbé (àpótí 3), tàbí tí ẹ n gbé ilé ọ̀fẹ́ (àpótí 4), o ní láti dáhùn abala keji ìbéèrè náà tani onílé rẹ?' Yan àpótí náà ti o yẹ (1, 2 tàbí 3) lati tọka bóyá onílé rẹ jẹ 'Onílé aládàníí', 'Ìjọba Ìbílẹ̀ ' tàbí 'Ti ẹgbẹ́ Aláàánú/Alájẹ̀ṣẹ́kù kọ́lékọ́lé' kan, lai ka pe tàbí bóyá o kò san gbogbo owo-ilé tàbí abala rẹ̀ funrarẹ, tàbí tí ó bá jẹ́ pe HSE tàbí ẹgbẹ́ míràn ni ó ba ọ san án.

**Ìbéèrè H4 – Tí o bá jẹ pe ẹ yá ibùgbé rẹ gbé ni, elo ni owo-ilé ti ìdílé rẹ n san?**
Tí ó bá jẹ́ HSE tàbí ẹgbẹ́ míràn ba san abala owó-ilé náà, iye ti ìdílé náà san nìkan ni ẹ ní láti kọ si í. Kọ iye náà perepere ni owó Euro, kí ó sìsàmì sí àpótí náà ti ó ba àkókò náà covered f.a. tí ìdílé rẹ bá n san €78.60 ní owó-ilé ní ọ̀sẹ̀-ọ̀sẹ̀, tẹ 79, kì o sì sàmì sí àpótí 1. Tí ó bá jẹ́ gbogbo owó-ilé rẹ ni ba ọ san, tẹ 0, kì o sì sàmì sí àpótí 1.

**Ìbéèrè 4 – Ìbáṣepọ̀**
A ṣe ìbéèrè ìbáṣepọ̀ náà ni ọna ti a fi le mọ àwọn ẹbí laarin inú àwọn ìdílé. Bi i ki àwọn ẹbí méjì wà ninu ìdílé kan wà lara àwọn nnkan ti a n sọ yìí. Fún àpẹrẹ, ìdílé kan to ni ọmọbìnrin tó dàgbà kan ti n gbé pẹ̀lú àwọn òbí rẹ̀ méjì le wà nibẹ̀ pẹ̀lú ọmọ ti ararẹ̀ kan, ni a ó kà gẹ́gẹ́ bí ìdílé ẹlẹ́bí méjì.

Àpẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí n fi bi a o se dáhùn ìbéèrè fún ọmọ náà tó wà ni iru ipo yìí, níbi tí àwọn òbí rẹ̀ ti jẹ Àwọn Ènìyàn 1 àti 2 lórí fọ́ọ̀mù náà, ti ọmọbìnrin tó dàgbà náà jẹ́ Ènìyàn 3, ti ọmọ tirẹ̀ sì jẹ́ Ènìyàn 4.

Sàmì sí ⊟ àpótí kan ṣoṣo fún ènìyàn kọ̀ọ̀kan.

| Ìbáṣepọ̀ ÈNÌYÀN 4 pẹ̀lú | | Àwọn ènìyàn 1 | 2 | 3 |
|---|---|---|---|---|
| Ọkọ tàbí ìyàwó | 1 | ▢ | ▢ | ▢ |
| Ẹnìkejì (ti o le jẹ ako-n-bábo kan náà pẹ̀lú ẹnìkejì) | 2 | ▢ | ▢ | ▢ |
| Ọmọkùnrin tàbí ọmọbìnrin | 3 | ▢ | ▢ | ⊟ |
| Ọmọ-orogún | 4 | ▢ | ▢ | ▢ |
| Arakúnrin tàbí arabìnrin | 5 | ▢ | ▢ | ▢ |
| Ìyà tàbí bàbá | 6 | ▢ | ▢ | ▢ |
| Òbí-àgbà | 7 | ▢ | ▢ | ▢ |
| Ìyà/bàbá-keji | 8 | ▢ | ▢ | ▢ |
| Àna-Ọmọkùnrin-/ Àna-ọmọbìnrin | 9 | ▢ | ▢ | ▢ |
| Ọmọ-ọmọ | 10 | ⊟ | ⊟ | ▢ |
| Ìbátan Míràn | 11 | ▢ | ▢ | ▢ |
| Alábàágbépọ̀ (àti ọmọ àgbàtọ́ pẹ̀lú) | 12 | ▢ | ▢ | ▢ |

**Ìbéèrè 7 – Níbo ni o maa n gbé ni gbogbo-ígbà?**
Ìbéèrè yìí n tọ́ka si ibi ti o maa n saaba fi ṣe ilé ni àsìkò Ètò-Ìkànìyàn náà. Tí o bá ti gbé ni àdírẹ́sì yìí ni lemọ́lemọ́ fún àsìkò ti ko din ni oṣù 12 siwájú Alẹ́ Ètò-Ìkànìyàn, pẹ̀lú èrò pe o si tun maa gbe níbí fún kò din ni ọdún kan, o ní láti sàmì sí àpótí 1 (NÍBÍ). Tí ibùgbé gbogbo-ìgbà rẹ ki i bá ṣe ní ibí sùgbọ́n ti ó jẹ níbòmíràn ní Ireland (Àríwá Ireland wà lara wọn) o ní láti sàmì sí àpótí 2 kí o sì kọ àdírẹ́sì rẹ ní-kíkún. Tí ibùgbé gbogbo-ìgbà rẹ bá jẹ ibòmíràn ní ilẹ̀ òkèèrè o ní láti sàmì sí àpótí 3, kí o sì so orílẹ̀-èdè gbogbo-ìgbà náà.

Ìtọ́nisọ́nà gbogbogbò náà jẹ pe ibùgbé gbogbo-ìgbà ènìyàn kan ni ilé tí ó maa n sun oorun ni alẹ́. Àwọn ìtọ́nisọ́nà isalẹ yìí ni o ní láti lò:

- Kí àwọn ti ki ì sí nílé láárin ọ̀sẹ̀ náà, ti wọn sì maa n pada si ibugbé ẹbí wọn ni awọn ipari-ọ̀sẹ̀ rí ilé ẹbí náà gẹ́gẹ́ bí ibùgbé gbogbo-ìgbà wọn.
- Kí àwọn àkẹ́kọ̀ọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ àti ilé-ẹ̀kọ́ sẹ́kọ́ndírì ti wọn n gbé ni ilé wọn, àti àwọn àkẹ́kọ̀ọ́ ìpele kẹta ni kọ́lẹ́ẹ̀jì tàbí yunifasiti rí rí ilé ẹbí náà gẹ́gẹ́ bí ibùgbé gbogbo-ìgbà wọn.
- Tí ènìyàn kan bá ti lo oṣù 12 tàbí pe o fẹ lo oṣù 12 tàbí ju bẹẹ lọ ní ilé-ẹ̀kọ́ kan, a jẹ́ pé ilé-ẹ̀kọ́ náà ni ibùgbé gbogbo-ìgbà ẹni náà.
- Tí ènìyàn kan bá n gbé deedee ju ilé kan lọ ninu ọdún náà, a jẹ́ pé ibi náà tí ó ti n lo ọ̀pọ̀ ìgbà inú ọdún náà ní yóò yàn gẹ́gẹ́ bí ibùgbé gbogbo-ìgbà rẹ̀.

**Ìbéèrè 8 – Níbo ni o n fi gbogbo-ìgbà gbé lati bi ọdún kan sẹ́yìn?**
Ìbéèrè yìí jẹ́ ti àwọn ènìyàn ti ọjọ-ori wọn jẹ́ ọdún 1 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn ìtọ́nisọ́nà náà tó ní í ṣe pelu Ìbéèrè 7, tun ní í ṣe ìbéèrè yìí náà. Tí ibùgbé gbogbo-ìgbà rẹ fún ọdún kan siwájú Ètò-Ìkànìyàn náà bá jẹ ibi kan náà títí di ìsìnyìí, àpótí 1 ni o ní láti sàmì sí (IBI KAN NÁÀ títí di ìsìnyìí).

**Ìbéèrè 9 – N jẹ̀ o ti gbé ẹ̀yìn-odi Ilẹ̀ Ireland nìkan fún odindi ọdún 1 tàbí jù bẹ̀ẹ̀ lọ?**
Ìbéèrè yìí jẹ́ ti àwọn ènìyàn ti ọjọ-ori wọn jẹ́ ọdún 1 tàbí jù bẹ̀ẹ̀ lọ. Tí ibùgbé gbogbo-ìgbà rẹ bá jẹ Ilẹ̀ Ireland, ti o sì jẹ́ boya:

- wọn bí ọ ní orílẹ̀-èdè yìí, tí o sì ti gbé ni ẹ̀yìn-odi lemọ́lemọ́ fún àkókò 1 ọdún tàbí jù bẹ̀ẹ̀ lọ, tàbí
- wọn bí ọ NÍ ILẸ̀ ÒKÈÈRÈ tí o sì ti gbé ni ẹ̀yìn-odi Ireland lemọ́lemọ́ fún àkókò 1 ọdún tàbí jù bẹ̀ẹ̀ lọ tàbí,

a jẹ́ pé àpótí 1 ni o ní láti sàmì sí (Bẹ́ẹ̀ ni). O tun ní láti kọ ọdún náà ti o gba ilé gbẹ̀yìn ní orílẹ̀-èdè yìí àti orílẹ̀-èdè náà ti ilé ti o gbé gbẹ̀yìn wà.

**Ìbéèrè 15 – Ṣe o n sọ èdè míràn yàtọ̀ sí Èdè Gẹ̀ẹ́sì tàbí Èdè Áírísì ní ilé?**
Tí o ko bá le sọ èdè míràn yàtọ̀ sí Èdè Gẹ̀ẹ́sì tàbí Èdè Áírísì ní ilé, o ní láti sàmì sí àpótí 2 (Bẹ̀ẹ kọ́) kí ó sìtẹ̀siwaju si Ìbéèrè 16. Ẹyí tumọ si pe awọn ti wọn le sọ Èdè Gẹ̀ẹ́sì àti/tàbí Èdè Áírísì nìkan ni ilé, kò nilo lati sọ nnkan kan nipa bi wọn ṣe gbọ Èdè Gẹ̀ẹ́sì náà tó.

**Ìbéèrè 16 – N jẹ́ o ni ọ̀kan nínú awọn ipò àìlera tàbí awọn ìṣoro ọlọ́jọ́-pípẹ́ náà ti a kà si isalẹ yìí?**
Fún anfaani ìbéèrè yìí, ipò àìlera tàbí awọn ìṣoro ọlọ́jọ́-pípẹ́ ni eyi ti o ti pẹ́ tàbí ti a ro pe yóò pẹ́ oṣù 6 tàbí ju bẹẹ lọ, tàbí ti ó maa n sẹlẹ deedee.

**Ìbéèrè 22 – Ṣe o maa n pèsè ìrànwọ̀ àtìgbà-de-gbà fún ọrẹ tàbí ara inú ẹbí kan tí ó ní àìsàn, ìṣoro ìlera tàbí àìpé-ara ọlọ́jọ́-pípẹ́ kan láìgba owó?**
Tí o bá maa n pèsè ìrànwọ̀ àtìgbà-de-gbà gẹ́gẹ́ bí olutọ̀ju kan, lai ka bóyá tàbí o kò si ni ara awọn ti n jẹ Anfaani/Ajẹmọ́nú Olutọ̀ju, o ní láti sàmì sí àpótí 1 (Bẹ́ẹ̀ ni) kí ó sìkọ ye wákàtí náà itọju fun ọ̀sẹ̀ kọ̀ọ̀kan.

**Ìbéèrè 25 – Kín ni ìpele ẹ̀kọ́/ẹ̀kọ́-ṣẹ́ náà (ní-kíkún-àsìkò tàbí abala-àsìkò) tó ga júlọ tí o ti parí di ìsìnyí?**
Àwọn ìsọ̀rí ti a juwe ninu ìbéèrè yìí tẹle náà Àgbékalẹ̀ awọn Ìwé-ẹ̀rí ti Orílẹ̀-èdè (NFÌBRÈ). Ẹ̀kunrẹ́rẹ́ àlàyé wà ni www.nfÌBRÈ.ie

Ẹ̀kunrẹ́rẹ́ àlàyé lórí FETAC, HETAC, awọn ìwé-ẹ̀rí okeere àti gbogbo awọn ìwé-ẹ̀rí míràn ní apapọ n bẹ ni www.census.ie

**Ìbéèrè 26 – Ẹ̀ka ìmọ̀ ẹ̀kọ́ tó ga jùlọ wo gan an gan an ni o ti parí ìkẹ́kọ̀ọ̀gboyè títí di ìsìnyí?**
Ìbéèrè yìí wà fun ìwé-ẹ̀rí ilé-ẹ̀kọ́ Lẹyin-Sẹ́kọ́ndírì nìkan. Tí o bá ni awọn ìwé-ẹ̀rí kan, ẹka ìmọ̀ ẹ̀kọ́ náà tó ga jùlọ nìkan ní ki ẹ̀ kọ sibẹ.

**Ìbéèrè 27 – Báwo ni o ṣe le ṣàpéjúwe ipò náà gan an tó ga jùlọ ti o wà lọ́wọ́lọ́wọ́ yìí?**
O ní láti sàmì sí àpótí kan ṣoṣo lati le yan ìsọ̀rí náà ti o rò pe ṣàpéjúwe ipò náà tó ga jùlọ tí ó wà. Tí o bá wa ni ìsinmi àìsàn tàbí ìsinmi ìbímọ, ti o si n gbidanwo lati pada si ẹnu-iṣẹ́ ni ipele kan, o ní láti sàmì sí àpótí 1 (N ṣiṣẹ́ ).

**Ìbéèrè 34 – Àdírẹ́sì ibi iṣẹ́ , ilé-ìwé tàbí kọ́lẹ́ẹ̀jì**
Àwọn ènìyàn tí wọn jade kúrò ninu ìdílé náà lati lọ ibi iṣẹ́, ilé-ìwé tàbí kọ́lẹ́ẹ̀jì ní láti fun wa ní orúkọ ní-kíkún àti àdírẹ́sì ibi náà.

Fún àwọn ọmọ ti n jade kuro ni ilé náà lọ si àwọn ìpèsè imurasilẹ̀-ilé-ìwé (f.a. ibi-itọju ọmọde, jẹ́-lé-ó-sinmi), ki ènìyàn ti n kọ fọ́ọ̀mù náà fun wa ni orúkọ àti àdírẹ́sì ìpèsè yìí ní-kíkún.